# Ìpinnu 1325 ti Àjọ Ààbò Àgbáyé: Àwọn Obìnrin, Àlàáfíà àti Ààbò

Àjọ Ààbò Àgbáyé,

Ní rírántí rẹsolúsọ̀n rẹ̀ 1261 (1999) ti ọjọ́ kẹẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n oṣù kẹjọ ọdún 1999, 1265 (1999) ti ọjọ́ kẹtàdínlógún  oṣù kẹsàn-án ọdún 1999, 1296 (2000) ti ọjọ́ kọkàndínlógún oṣù kẹrin ọdún 2000 àti 1314 (2000) ti ọjọ́ kọkànlá oṣù kẹjọ ọdún 2000, àti àwọn ọ̀rọ̀ akànsọ ààrẹ rẹ̀ àti ọ̀rọ̀ tí ààrẹ rẹ̀ sọ fún àwọn oníròyìn ní ọjọ́ àyájọ́ fún ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin ti àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé àti ti Àlàáfíà àgbáye ní ọjọ́ kẹjọ oṣù kẹta 2000 (SC/6816),

Ní ríràntí i ìlérí i àkànṣe ìkéde àti ọ̀nà fún iṣẹ́ àmúṣe ti Beijing (A/52/231) pẹ̀lú u àwọn ìlérí tí ó wà nínú ìwé àbájáde ti Àkànse ìpàdé e gbogbogbòò kẹtàlélógún ti àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé tí àkórí i rẹ̀ jẹ́ “Women 2000: Gender Equality, Development and Peace for the twenty-first century” (A/S-23/10/Rev. 1), pàápàá jùlọ àwọn tí ó kan àwọn obìnrin àti rògbòdìyàn àfi-nnkan-ìjà-ogun ṣe,

Pẹ̀lú fífi èròngbà àti  àwọn òfin ìdásílẹ̀ ẹ àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé àti lájorí iṣẹ́ ẹ Àjọ ètò ààbò àgbáyé lábẹ́ òfin fún ìtẹ̀síwájú àlàáfíà àti ààbò àgbáyé,

Ní fífẹ̀dùn-ọkàn hàn pé àwọn ará ìlú, pàápàá àwọn obìnrin àti àwọn ọmọdé ni ó pọ̀ jù nínú àwọn tí  ó ń jìyà rògbòdìyàn àfipáṣe , gẹ́gẹ́ bí i ẹni ogun ṣí nípò àti ayálùúgbé àti pàápàá ẹni tí àwọn abipá àti ajagun n dojú kọ, àti ní ṣíṣàkíyèsí ipa tí nnkan wọ̀nyìí ní lórí i àlàáfíà àti ìbára-ẹni-làjà,

Ní títún-gba ipò pàtàkì tí àwọn obìnrin ń kó nínú dídabọ  àti yíyanjú ìjà ìgboro àti ní mímú àlàáfíà gbòòrò, àti ní fífi pàtàkì ìkópa wọn nínú àwọn akitiyan lórí i ìtẹ̀síwájú àti igbéga àlàáfíà àti ààbò,  àti láti jẹ́ kí ipa wọn ó pọ̀ sí i nínú ìpinnu ṣíṣe lórí i dídabọ  àti yíyanjú rògbòdìyàn,

Ní títún-gba pé ó yẹ láti tẹ̀lé gbogbo òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lágbàáyé tí ó dáàbò bo ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin àti t'àwọn ọmọbìnrin lásìkò àti lẹ́yìn in rògbòdìyàn,

Ní títẹnumọ́ bí ó ṣe ṣe pàtàkì tó fún tọ̀tún tòsì láti rí i pé pípalẹ̀ ẹ àdó onítàkúté mọ́ àti àwọn ètò fún jíjẹ́ k'áyé mọ̀ nípa àdó onítàkúté náání àwọn obìnrin àti àwọn ọmọdébìnrin,

Ní mímọ bí ó ṣe ṣe wúlò tó láti fojú u takọ tabo wo àwọn ètò ìmálàáfíà-wá, nípa ṣíṣàkíyèsí àkànṣe ìkéde ti Windhoek àti ti ètò àmúṣe fún ọ̀rọ̀ makọmabo nínú àwọn ètò o ìmálàáfíàdúró ti Namibia (S/2000/693),

Ní títún-mọ pàtàkì i àwọn àbá tí ó wà nínú àwọn ọ̀rọ̀ ààrẹ fún àwọn oníròyìn ní ọjọ́ kẹjọ oṣù kẹta ọdún 2000 fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àwọn aláàbò, àti ètò ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àwọn obìnrin àti àwọn ọ̀dọ́bìnrin,

Ní mímọ ìpalára tí rògbòdìyàn àfipáṣe ń fà fún àwọn obìnrin àti ọmọbìnrin, àti pé, ṣíṣètò láti ní ìmọ̀dájú nípa ìdáàbò àti ìkópa kíkún nínú ètò àlàáfíà lè kópa ńlá nínú ìfẹsẹ̀múlẹ̀ àti ìgbéga àlàáfíà àgbáyé, Ṣíṣàkíyèsí i bí ó ṣe ṣe pàtàkì tó láti ṣàkójọ ẹ̀rí tí ó wà lórí i ipa tí rògbòdìyàn àfipáṣe ń ní lórí àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin,

1. Rọ ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ láti fi kún aṣojú àwọn obìnrin nínú ìpele kọ̀ọ̀kan tí a ti ń ṣe ìpinnu lórílẹ̀ èdè, ní ẹkùn kọ̀ọ̀kan, àti ní ibi àjọ kọ̀ọ̀kan ní àgbáyé, àti pàápàá láti ṣe ètò láti dẹ́kun, láti kappa, àti láti yanjú rògbòdìyàn;

2. Fífún akọ̀wé àgbà ní ìwúrí láti ṣiṣẹ́ lórí i ètò tí ó là sílẹ̀ fún àmúṣe (A/49/587) tí ó n pè fún pípọ̀ sí i ìkópa àwọn obìnrin nínú ìpinnu ṣíṣe lórí i yíyanjú u rògbòdìyàn àti síṣe ètò àlàáfíà;

3. Rọ akọ̀wé àgbà láti yan àwọn obìnrin sí i gẹ́gẹ́ bí i aṣojú pàtàkì àti ajẹ́lẹ̀ láti má a ṣe àwọn nnkan rere lórúkọ ọ rẹ̀, ní àtàrí èyí ìpè tún lọ sí ọ̀dọ̀ ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ láti pèsè e àwọn obìnrin tí ó kún ojú òṣùnwọ̀n fún akọ̀wé àgbà láti wà nínú ìwé àkọsílẹ̀ tí à ń yẹ̀wò déédé;

4. Tún rọ akọ̀wé àgbà láti má a wá ọ̀nà láti mú kí ipa àwọn obìnrin ó pọ̀ sí i nínú ètò àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé pàápàá láàrin àwọn aṣàkíyèsí àwọn ológun, àwọn ọlọ́pàá alágbádá, àti àwọn tí ó ń ṣiṣẹ́ fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn;

5. Fífi ìṣetán an rẹ̀ hàn láti fi ètò o makọ-mabo sínú ètò o ìmáláàfíà-wá àti láti rọ akọ̀wé àgbà láti rí i dájú pé ọ̀rọ̀ ọ makọ-mabo n jẹyọ nínú iṣẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ ìgboro níbi tí ó bá ti yẹ;

6. Fẹ́ kí akọ̀wé àgbà pèsè e ìtọ́ni fún ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ nípa ìdáàbò bo'ni, ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, àwọn ohun tí àwọn obìnrin nílò àti pàtàkì i kóbìnrin nípa nínú àwọn ètò ìmáláàfíà-wá, ìmáláàfíà-gbèrú sí i, láti pe ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ láti fi àwọn kókó yìí àti ọ̀rọ̀ lórí i ìkọ́ni láti fura lórí àrùn un kògbóògun (HIV/AIDS) sínú un ètò o orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan fún àwọn ológun àti àwọn ọlọ́pàá alágbádá ní ìgbaradì fún ìránjáde, kí akọ̀wé àgbà sì rí i dájú pé àwọn alágbádá inú àwọn òṣìṣẹ́ amáláàfíà-wá náà ní irú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kan náà;

7. Rọ ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ láti fi kún owó tí wọn ń fínnufíndọ̀ ná fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lórí ọ̀rọ̀ ọ makọ-mabo pàápàá àwọn ètò tí àjọ ìsọ̀kan àgbàyé àti èyí ti àjọ ìsọ̀kan àgbàyé fún àwọn ọmọdé àti kọmísánnà àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé fún àwọn ẹni-àjálù-ṣí-nípò ń náwó lé lórí;

8. Pe gbogbo àwọn akópa nínú ìṣààtò àlàáfíà láti ṣàmúlò o èrò o makọ-mabo fún ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́: (a) Àwọn ohun tí àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin nílò gẹ́gẹ́ bí i ẹnìkọ̀ọ̀kan, nígbà ìpadàsílé, ìbẹ̀rẹ̀-ayé-ọ̀tun, àti fún ìmúdàgbà-sókè àti ìtúnlùúṣe lẹ́hìn in rògbòdìyàn; (b) Àwọn ètò tí ó ṣèrànwọ́ fún ètò tí àwọn obìnrin ìgbèríko bá

ń ṣe fún àlàáfíà àti ìyanjú u rògbòdìyàn àti èyí tí ó jẹ́ kí àwọn obìnrin ó kópa nínú mímú àwọn ìpinnu lórí ètò àlàáfíà wá sí ìmúṣẹ; (d) Àwọn ìlànà tí ó ń jẹ́ kí ààbò àti ọ̀wọ̀ wà fún ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin pàápàá lórí ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ òfin orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan, ètò ìdìbò, ọ̀rọ̀ ọlọpàá, àti ètò ìdájọ́.,

9. Pe gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn nínú un rògbòdìyàn àfipáṣe láti bọ̀wọ̀ fún àwọn òfin àgbáyé lórí i ẹ̀tọ́ àti ààbò àwọn obìnrin àti ọmọbìnrin tí wọn kìí ṣe ológun, pàápàá àwọn ohun àìgbọdọ̀-ma-se tí ó wà fún wọn lábẹ́ ẹ *Geneva Convention* ti 1949 àti àwọn ojúṣe mìíràn ti 1977, àti èyí tí ó wà nińu un *Refugee Convention* 1951 àti àfikún òfin ti 1967, àjọ̀dún àjọ ààbò karùn un- ìwé ìkéde ìròyìn in SC/6942 ìpàdé e 4213, ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kẹwàá, ọdún 2000 lórí i dídẹ́kun gbogbo ìwà a ìdóbìnrin-yànjẹ ti 1979 àti àwọn òfin wọ̀fún ti 1999 àti ti àjọ̀dún àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé lórí ẹ̀tọ́ àwọn ọmọ ti 1989 àti ti àwọn òfin wọ̀fún méjì i ti ọjọ́ karùndínlọ́gbọ̀n oṣù karùn-ún ọdún un 2000, àti láti fi àwọn tí ó yẹ nínú òfin Rome Statute ti ilé ẹjọ́ fún àwọn ọ̀daràn àgbáyé;

10. Pe gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn nínú un rògbòdìyàn àfipáṣe láti ṣe àwọn èto tí ó yẹ láti dáàbò bo àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin kúrò lọ́wọ́ ọ àwọn ìwà ipá bí i ìfipábánilò àti àwọn ìwà ìbániṣe lọ́nà àìtọ́ mìíràn, àti àwọn ìwà ipá mìíràn tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ lásìkò o rògbòdìyàn àfipáṣe,

11. Tẹnumọ́ ojúṣe gbogbo orílẹ̀ èdè láti fòpin sí ìmẹ́ṣẹ̀jẹ àti láti máa pe àwọn tí ó bá ṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ ìpanilọ́pọ̀yanturu, ẹ̀ṣẹ̀ sí ọmọnìyàn, ẹ̀ṣẹ̀ ọ̀ràn ogun pàápàá ìfipábóbìnrin àti àwọn ọmọbìnrin lo, àti pàápàá, nígbà tí ó bá ṣeéṣe kí wọn má jẹ́ kí àwọn tó bá ṣẹ irú ẹ̀ṣẹ̀ yìí rí ìdáríjì gbà,

12. Pe gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn nínú un rògbòdìyàn àfipáṣe láti bọ̀wọ̀ fún àbùdá alágbádá àti ajẹmọ́-ọmọnìyàn an àwọn àgọ́ àwọn ẹni-ogun-ṣí nípò àti láti fi àwọn ohun tí àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin nílò àti ìṣẹ̀dá a wọn sọ́kàn, àti ríràntí i ìpinnu un rẹ̀ ti ọjọ́ kọkàndínlógún oṣù kọkànlá, ọdún un 1998;

13. Ṣèwúrí fún gbogbo àwọn ẹni tí ó ń kópa nínú ètò ìkó-nnkan-ogun-sílẹ̀, títú-ọmọ-ogun-ká àti ìfara-ẹni-mọlé láti kíyèsí ohun tí àwọn obìnrin àti àwọn ọkùnrin tí ó ti jagun rí nílò, àti láti kíyèsí ohun tí àwọn ènìyàn tó gbẹ́kẹ̀ lé wọn nílò;

14. Tún sọ pé àwọn ṣetán láti gbé igbésẹ̀ tí ó bá yẹ nígbàkigba tí wọ́n bá fẹnukò láti ṣe ohun kan lábẹ́ ẹ atiku 41 ti ofin àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé lát mọ ipa irú ofin bẹ́ẹ̀ lórí àwọn àwọn ènìyàn ìlú, àti pẹ̀lú, kí wọ́n fi ohun tí àwọn obìnrin àti àwọn ọmobìnrin nílò sọ́kàn láti lè yọ wọ́n sílẹ̀ lábẹ́ irú òfin bẹ́ẹ̀;

15. Fífi ìṣetán an rẹ̀ hàn  láti rí i dájú pé iṣẹ́ àjọ ààbò àgbáyé ka ọ̀rọ̀ ọ takọtabo àti ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin sí nípa fífọ̀rọ̀ lọ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin ní ìlú kọ̀ọ̀kan àti ní àgbáyé;

16. Pe akọ̀wé àgbà láti ṣe ìwádìí lórí i ipa rògbòdìyàn àfipáṣe lórí àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin, ipa àwọn obìnrin nínú ètò ìmálààfíà-dàgbàsókè àti ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ takọtabo nínú ètò àlààfíà àti ìyanjú u aáwọ̀ òun rògbòdìiyàn, wọ́n sì tún pè é láti kọ ìwé ìjábọ̀ ìwádìí lórí i àbájáde ìwádìí yìí fún àjọ ààbò àgbáyé kí ó sì fún àwọn ìpínlẹ̀ tí ó wà nínú àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé náà;

17.  Bèèrè lọ́wọ́ ọ akọ̀wé, nígbà tó bá tọ́, láti máa fi ọ̀rọ̀ tó bá jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ takọtabo nínú un gbogbo ètò ìmálààfíàdúró àti àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹmọ́ àwọn obìnrin àti àwọn ọmọbìnrin sínú ìwé ìjábọ̀ ọ rẹ̀ fún àjọ ààbò àgbáyé;

18. Pinnu láti tẹ̀síwájú láti máa ṣakitiyan lórí i kókó ọ̀rọ̀ yìí.